ASOJẸ ORO

Olore ko ni ku, olore ko ni run, 'gba olore ko ni fọ, awo olore ko ni ra, atẹpa oju atẹpamọsẹ kuiọ kujọ, kujọ ore, towotomo lo nyale olore.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

OWE YORUBA

Nibiti o ṣẹfifa lẹle lo ndari igoẹ si, ibiti o ba wu olowo ẹn lo iran ni lọ. Afẹfẹ lo nso ori igi yẹr yẹr ifufu lo nṣẹ ori agbọn waroko.

VOL. XII No. 672. LAGOS, SATURDAY, APRIL 30, — MAY 7, 1960. KỌBỌ MEJI (2d)

# Awon Olotu Wa Nlo Se Ipade Asepari Eto Ominira Ile Nigeria

**Irohin ta siwa leti fẹrẹn wipe Ọlọla Prime Minister Sir Abubakar Tafawa Balewa nṣiwaju awọn Ikọ lọ silu Oyinbo lọjọ ọsẹ (Sunday) ọjọ kini oṣu May 1960. Ṣugbọn Gomina agba yio ṣiwaju Prime Minister lọ. Loni Saturday ni yio lọ.**

Alhaji Muhamad Ribadu ati Oloye F. S. Okotie-Eboh yio ba ọkọ ofurufu lọ ni ọjọ Alaruba (Wednesday) ọjọ kẹrin oṣu May, 1960.

Awọn enia meji ti awọn jẹ onimọran ti awọn tun mba ọkọ lọ ni ọjọ Alaruba na ni Ọgbẹni T. O. S. Benson ati Zanna Bukar Dipcharima, ẹniti o tun nlọ pẹlu ni Ọgbẹni E. I. G. Unsworth.

Ni gẹrẹ ti Prime Minister ba lọ lọjọ Sunday Alhaji Ribadu ni yio ma dele de e, ti Ribadu ba si lọ, Alhaji Inua Wada ni yio tun dele de e Prime Minister titi yio fi pada wa sile.



Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa



Alhaji Mohammed Ribadu

Eyi ni yio jẹ alọ gbẹhin silu Oyinbo ti awọn Olotu ilẹ Nigeria ti nlọ ṣe eto iṣelu ti nwọn ti bẹrẹ lati nkan bi ọdun mẹfa s'ẹhin.

Alọ a dara, abọ a sunwọn o



Chief F. S. Okotie Eboh

THE NATIONAL BANK
Of Nigeria Limited
Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA
22 Branches Throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatves in London
E. A'kinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.

## Ijoba Gba Lati Pese Oja Fun Awon Obinrin

Ọgbẹni I. J. Dosunmu ọkan ninu awọn aṣoju ilu Eko lo da ẹbi fun ijọba alapapọṣọ wipe awọn lo ṣe idalọwọkọ fun ajo igbimọ Lagos Town Council nibiti awọn ẹgbẹ Action Group ti ko jẹki nwọn ti kọ ọja fun awọn obinrin ọlọja ti o ntaṣọ nilu Eko.

Ọgbẹni Dosunmu tẹsiwaju ọrọ yi si eti igbimọ alatori ki nwọn ba le mọ iru ipo ti awọn obinrin alaṣọ ti ko ni sobo, ti nwọn npatẹ kakiri ojude wa ati awọn ọlọja miran pẹlu. Awọn ọja ti o mbẹ ni ilu Eko nisisiyi ko gba awọn obinrin ti o nta ọja nwọnyi nilu Eko. Aṣoju ilẹ Eko paapa si mọ bẹ.

Mo tilẹ fẹ bere ire kini tabi kini ajo igbimọ Town Council ni lokan rẹ lati ṣe fun awọn obinrin nwọnyi, o wa tabi ko tilẹ si, Ijọba si dahun pe o wa.

Ninu awọn ẹkọs'le Ọgbẹni Rapson Oluwadi nipa awọn ọja ilu Eko, o sọ wipe, iṣọ ti a kọ si ọja gbogbo ti o mbẹ nilu Eko, ko to fun awọn obinrin ọlọja lati ma ta ọja wọn. Ko nṣe oni ni ọrọ awọn obinrin ọlọja nwọnyi ti bẹrẹ, lati ọdun 1954 lo ti bẹrẹ. Gbogbo eto ti ẹgbẹ Action Group ti ṣe fun awọn obinrin ọlọja na, ijọba apapọ se ti ba eto na jẹ.

(Iyoku d'oju ewe to mbọ)

## Ero Meka Odun Yi Po Jojo

Agbo irohin lati odo nyinuo al bojuto awon ajeji ti o nmo ilu wa ati awon ti o njade wipe, nwon gba gbo pe awon ero ti o nlo si Ilu... Oguna Liduo n., yio po gidigidi ninu odun 1960 ti a wa yi.

Lati ibere odun 1960 titi de ipari osu March, ti a kiran odun kekere, iyen ni odun awe, iye awon enia ti o wa fi oruko sile pe nwon nlo si Meka je egbaijileloguran o le ogorin (4,880).

Bese ko nse iba awon enia nwonyi lo nibere lati lo si ilu Meka, opolopo won lo si ku lehin ti nwon ofe l... Sugbon lehin osu meta yi, iba awon enia ti nwon si wa fi oruko sile niyen.

## Awon Olosa Wo Ilu Asaba

A gbo irohin wipe awon olosa ti wo igboro ilu Asaba, awon olopa na, gegebi a ti gbo je ara awon t... olopa gbogun ti, ti nwon si le jade kuro ni ilu Onitsha, nigbati nwon le won kuro, enu ilu Asaba ni a gbo wipe nwon tan won si.

Awon olosa nwonyi di eru jeje fun awon olokp ti o nfe sode odo-Oya lati Onitsha si Asaba.

Obinrin kan ti o wo oko soda lo si Onitsha lati ilu Asaba. awon ole na ni ki o duro nigbati obinrin na si ko lati duro, awon Olosa yinb... Sakabola la a, ibon yi ba obinrin na ni ... ese o si se ese na. Awon olopa wa olosa na ni awati.

Awon ... Iwo-orun ran ogun awon olopa lo si Asaba lati lo kongo fun awon olosa na, ibiti awon olopa fi se ibudo ni Cable Point, a gbo pe awon olopa ... si.

## OBINRIN TO GBA ERU OLE DANI WO EWON

—o—

ILESHA. Obinrin kan ti oruko re nje Adisa Kano ni agbo wipe awon olopa jale, awon si ko eru ti nwon ri ko si odo re o gba a ... fi pamo.

Ibe ni awon Otelemuye ti fimu finle titi owo fi te Adisa. Obinrin na tojo wipe on ko jale, ese ni gwon wa ko si odo on.

Owe Yoruba kan so wipe "Agbepo l'ale ko jale, bi enit o gba lowo re". Nig'ati ejun sisun obinrin na po, adajo se anu re, nigbon oni ki o lo si ewon odun meta. Kotu ibile Ilesha lo da ejo na.

## Egungun Kan Ku Sita Gbangba

A gbo irohin lati ile Kaba wa wipe Egungun kan ti nwon npe ni Olupiyo Iya ku si ibi ti o gbe ujo ti o ngba kobokobo ni abule kan ti nwon npe ni Iyagbede nitori ese ti o koja lo.

Eni ti o gbe egungun na je omo orukan bi o ba gbe ago re a ma korin ati ma jo pelu ki o ba je ri owo ile a... re,

Eni kan ti o je alejo ti ko mo ara Iyagbede so wipe laipe yi ni on ti egungun Olupiyo Iya, ni adugbo won ni Aiyegunle ti o so fun on pe, ki on lo so ni adugbo won pe, egbogi ni nwon fi pa on gbogbo awon egbe oniegun lo sopanpa lati wadi enini o sese buruku na. Oro na wa lodo awon olopa, nwon nse iwadi lowo.

## Enia Kole Bimo Lai Loyun

—o—

**Obinrin kan ti o sese bi omo oponlo lo ma ejo lo si odo awon olopa wipe omo ti on sese bi ti koiti to osu kan ni on fi se awati ki nwon jowo gba on.**

**Lesekanna awon otelemuye ti be si ode, ibe ni awon ti ri Amoke ti o gbe omo tuntun pon si ehin Awon olopa pe e, nwon ni ki o wo moto nwon si mu lo si ago won.**

(Woyeka loju ewe keje)

## Awon To Lo Se Eto Ilu Ni London




Awon iko ti a nwo sinu aworan yi ni awon ara ile elekuesu Mauritius ti nwon gunle si idi oko ofurufu ni ilu Oyinbo nigbati nwon lo jiroro nipa oro ilu won. Oruko won niwonyi: Ogbeni R. Seeneevassen, Dr. S. Ramsgoolam, Dr. L. A. Celestin, Ogbeni A. G. Sauzier, J. M. Koeng, A. R. Mohamed, J. G. Forget J. G. Rosemont ati Sir Robert Scott.


# Polowo Oja Re Sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe



ARADAN NERVIGORA

Ogun oje pataki fun imarale agba ati arumo pipo fun awon alaya pipo O dara fun inarun eje didu, isokun eje, gbigbon owo, ailesun, ailokun ninu ati inafe arun bawonni. O je ajidewe fun awon ti agbara won ndinku. On na gan ni oruko re yi lo ti o fi di "Afose ko bi ojo". 5/6d. pere pelu owo oko 1/6d e.g. 7/- Post Free.

THE EGBA TRADING ARADAN STORES
112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street
P.O. BOX 2. Ebute-Metta
Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.

## Ologose Ati Kannakanna Jumo Nsore

—O—

Ni igba kan, ni aiye atijọ awọn ẹiyẹ meji nṣore pọ, ekini ni ẹiyẹ Ologose, ekeji ni ẹiyẹ Kannakanna, ọrẹ won pọ de'po ti ẹiyẹ Ologoṣe fi pe ọrẹ re ẹiyẹ Kannakanna wipe, ko tọ bẹni ko si yẹ ki awon ma ṣe igbanraye kiri, ki o ie wipe ni ajojumọ ni awon yio ma fi tororẹ

O fi imọran siwaju ọrẹ re pe ki o jẹ ki awon juma lọ da oko, ki awon ṣe ọgbin ohun jijẹ nipa bẹ, awon yio ni ifokanbale. Ẹiyẹ Kannakanna gba, o fi ọkan ọrẹ rẹ, ẹiyẹ Ologoṣe bale, o so fun pe ki o lọ bẹrẹ si sa oko na, on yio ba lẹnu iṣe na.

Nigbati Ologoṣe sa oko tan, o pe ọrẹ ki o wa ki awọn dana sun ọkọ na, o tun sọ fun bakanna wipe ti o ma ṣe aiṣo, on mbe. O tun pe ki o wa ki awon ko ẹbe oko na, ọgbọn ẹwẹ lati ṣe olẹ ni ọrẹ Ologose tun da, ti ko fi de bẹ titi ti iṣe oko fi pari.

Nigbati ohun ọgbin oko bẹrẹ si jade, onjẹ de, nigbana ni ẹiyẹ Ologose tunpe ẹiyẹ Kannakanna ọrẹ rẹ pe, isu ata agbado alamọ, awọn ẹpa, erẹe tabo ẹwa pẹlu ewe'bẹ ti nparada.

Ki ilẹ ọjọ keji to mọ, ẹiyẹ Kannakanna ti de oko, ibiti o nfi ọwọ wa idi iṣu, ti o nṣe ayẹwo omo agbado ni Ologose gbe wa ba l'oko. Ibẹ ni ẹiye Ologoṣe ti bere si fi ọrẹ re se yẹye, ni o fi nke hayi lati ojo na pe: "Sişe koro, jije ọfe"!.

## Oro Mosalasi Di Oro Kotu Nilu Onitsha

Orọ Mọṣalaṣi ilu Onitsha di ohun ti a ni lati gbelọ si kota lori wipe emi lo ni Mọṣalaṣi, ko nṣe iwọ.

Apakan awọn Imale ilu na, kọwe ranṣẹ si adajọ wipe, ki o ṣe ikilọ fun Alhaji Imoru Yuṣawu wipe ilu lo ni Mọṣalaṣi Jimọ na, ko nṣe ti awọn Hausa, nitorina ẹnikẹni lo ni ẹtọ lati kirun nibẹ, ẹnikẹni ko gbọdọ kọ ile miran kun laigba aṣẹ Jọnma Musulumi.

Nigbati adajọ wadi ẹjọ na lọ ẹwa sẹhin, ori pe ẹjọ Alhaji Yuṣawu jare, oni ki Jọnma Musulumi lọ san owo irin ẹsẹ £178 10/- fun Alhaji na.

"Adajọ na sọ wipe gbogbo awọn ẹlẹjọ awọnyi, alejo ni awọn jẹ ni Onitsha, ṣugbọn gẹgẹbi ọrọ ti on gbọ lẹnu awọn ẹlẹjọ na, on gbagbọ wipe awon ẹbi Mgbelekeke lo fun Malam Haruna ni ilẹ na ki awọn to kole si lori.

Nigbati Mallam Haruna si ku ẹwẹ ni Alhaji Yusawu ba gori halefa rẹ, nitorina on gba wipe Yuṣawu lo ni Mọṣalaṣi on lo si lati yan ẹnikẹni ti o ba ni sina Mọṣalaṣi na.




## Alabojuto Ilu To Gba Ebun Alafia



Ẹniti a nwon yi ni Ọgbẹni Phillip Noel-Baker, on kanna ni Sẹkitẹri igbimọ ẹgbẹ gbogbo agbaiye (Commonwealth) ou lo gba ebun Mẹdali fun alafia (Nobel Peace Prize) ni ọdun 1959, nitori pe oponọpa to fi yọ fun alafia agbaiye ninu igbesi aiye rẹ.

### ỌKỌ OFURUFU KAN JA LULẸ NI KONGO

A Gbọ irohin wipe, ọkọ ofurufu kan ti o ni ero alagbefo mẹrin, ti o nlọ si Kongo lo ja lulẹ lori irin ajo rẹ, gbogbo emi marundilogoji ti o wa ninu ọkọ na rasu a tilẹ gbọ pe ọmọ titun jojolo kan mbẹ larin awọn ero na.

Enia mẹsan ni a gbọ pe awọn nṣiṣẹ ninu ọkọ na, o si ko awọn ero mejidinlọgbọn, awọn ọmọde meji si mbẹ ninu ile alaisan ti awọn koiti ku rara.

Awọn ara Kongo ni a gbọ pe, awon poju ninu awọn ero oko na, ara Belgium wa nibẹ, awon ara Italy wa nibẹ, awon ara ilẹ Jamani wa nibẹ pẹlu. Oṣẹ kan wa nibẹ. Orukọ ti nwọn npe oko na ni Skymaster.

Ki Oluwa ma jẹki a rin ọjọ t'ebi npona.

## Ipade Awon Baba-lawo

Ajọdun ọdun Ipẹlẹ ti ọdọọdun ni aọ ṣe ni agbara Ẹledá ni ọjọ Aiku 15th May, 1960 ni ile Ijọba Olodumare". Ni ayika onile odu ti Oduduwa gaju ilo ni ilu Ifon.

Ninu apejọ ajọdun wa odun ni asiko ilu Ijoba wa, ki a lebe gidigidi fun ominira ti a fe gba ni 1st ọwara (October) 1960, po ki o ja ni rere fun gbogbo wa.

Ọdun-ọdunni ayabo.

E POLOWO OJA NYIN SINU RE, KI E SI MA KA A FUN IROHIN ALADUN

# ELETI-OFE

A-NIJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI-OFE, LAGOS
P. O. Box 487 Phone 23370

VOL. XII. NO. 673. SATURDAY APRIL 30 — MAY. 7, 1960


## Agbalagba Ki Wa Loja...

Ki ori ọmọ titun wọ", ni owe awọn baba nla wa Yoruba. Ohun ti o mu wa pa owe ti a fi ṣe akọle wosiki wa ọsẹ yi fun ẹnyin ọkawe wa ni ti ariwo ojojumọ ti a ngbọ lati ile igbimọ apapọse wa nipa owo ilu ati eyiti ijọba ngbero lati wa ya lati awọn ilu okere.

Loja tiwa, o yẹ ki awọn ẹgunna gbomgbo ti o mu opo ijọba wa dani, fi eti si ọrọ ijọ Alatako, paapa ọrọ alaye eto ọna ni owo ti ṣe le mu wọ apo ijọba ti Olori ijọ Alatako, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ sọ ti o si fi ye ile igbimọ yekeyeke, ki awọn si ṣiṣẹ le lori gẹgẹbi ilana ti o ṣe fun wọn, ki ijọba ominira ti a o gba yi le tu u ki o si ba a fun gbogbo ilẹ Nigeria.

Aki Oloye wa, Ọbafẹmi Awolọwọ, ẹku afiyesi; "agbalagba ki wa l'ọja k'ori ọmọ titun wọ o.

## ELETI-OFE D'ARABA




## IṢELẸ NLA JA NILẸ PERSIA

—o—

Irohin iṣelẹ nla to ja ni ilu meji, ilu Lar ati ilu Garash ni a gbọ wipe o fẹrẹ to ẹgbẹdogun emi ọmọ enia to ragu sinu ilẹ ninu awọn ilu mejeji na. Awọn enia to sọ di alainile lori fẹrẹ to ẹgbaxan enia.

Ko seku ile kansoṣo ni duro ti ko wo lulẹ, awọn enia ti ko ku npagọ sinu papaa (fields) kiri ni. Iṣelẹ yi pọju eyiti o ṣe nilu Agadir nilẹ Moroko ti agbọ pe ẹgbafa enia ni ọmi wọn parẹ sibẹ niwọn ọsẹ bi mejọ sẹhin.

## TANI LE ṢE GẸGẸBI BABA RẸ.

Olotu.

Gba mi laye lati ṣe atunṣe ede yi lọdọ awọn ọkawe rẹ, boya a si le ri ẹniti o fẹ ṣe bi baba rẹ. A si gbọ wipe ọmọ ti ko ba ṣe bi baba rẹ ti nṣe, ko nṣe ọmọ atata.

Ibere 1. Awọn baba rẹ a ma bọwọ fun Olorisa, nwọn si nteriba fun Orisa paapa. Njẹ lode ti oni, iwo ha le ṣe bi baba rẹ ti nṣe?.

Ibere 2. Laiye ijoun ti awon baba rẹ ma ndira bi awon Akogun pẹlu orin bayi pe "Ijalẹ ṣe bi o ti nṣe" nigbati nwon nlo roko, lode ti oni iwo ha le ṣe bi awon baba re ti nṣe ?.

Ibere 3. Nigba lailai ti awon baba rẹ ma njade lo si ode ijo, ti nwon nlọ aṣo aran ati aṣo oke mọdi, ti nwon nwo ewu singileti, ti nwon nwe gele bi obinrin, nje iwo ha le da iru ara ti baba re nda na?.

J. J. Olokundun.

## Enia Dudu Ti o Nsiṣe Ni Afin Oba Gesi



Ẹni ti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni J. B. Ọduntan, omo ilẹ Yoruba ti a to dagba nilẹ Ghana, o kowe pari nibẹ ki o to tun le ku ẹko ni ile ẹko giga ti Oxford. Ki o to di okan ninu awon Onirohin Ọba Gẹsi, o ti koko jẹ ọga kan nibi iṣe Oniwe Irohin ijọba, nilu Accra. Ọgbẹni Oduntan na ni a nwo ti o nla arin ẹgbẹ Ọba koja lo si enu iṣẹ rẹ, Ṣoja ti o duro ti o gbe ibon dani ni eyi ti o nṣọ afin Ọba nilu Oyinbo.

## Itan Anobi Lutu

Apa keta
Lati owo Lemomu Ajakuta

Nigbati Anobi Buramo le baba ti o nsin orisa Ina lo tan ni Olorun ba a wipe ohunkohun ti o ba wu enikeni lole sin, ki o mase tun le won lo mo. Ni ojo die si, ni awon alejo meta kan tun de Anoli Buramo si se won ni alejo.

Bi awon alejo meta na ti jeun tan, nwon so asotele fun Buramo wipe niwoyi amodun yio bi omokunrin kan lati odo Sarata lyawo re, eyi ni Sarata gbo ti o si bu si erin gbagba.

Ohun ti o fa a ti o fi rerin ni wipe, o ti di agba, ti ko si lenu okunrin mo, Anobi Buramo paapa ti le ni ogorun odun, awon mejeji ko le ta bi agbado mo, Nitorina, nigbati awon alejo na gbo wipe Sarata fi won rerin, nwon so fun Anobi Buramo pe bi o ba bi omo na tan, Anobi ni yio je ki o si so oruko re ni Isaku.

Awon alejo meteta di de, nwon si nlo. Anobi Buramo pase won siwaju, Nigbati won de iwaju ni nwon tu asiri ibiti nwon nlo fun wipe, Olorun lo ran awon nise lo lati se iparun awon enia Anobi Lutu, Nigbati Anobi Buramo gbo ara re bu mo aso nitori ibe ni Anobi Lutu wa, ( Koiti pari ).

## AWON OLOPA PA ONISUNMOMI MERIN

—o—

YAWENDE. Awon eya eya kan ti won ngbe ija Sunmomi lo kakiri ile awon Yawenda ni agbegbe ile Kamerun ni a gbo wipe nwon ya wo ilu kan nile Yawende, nwon kolu awon Hausa ti o ngbe ilu na, nwon pa won ni ipakupa nwon se oyinbo kan lese, nwon yinbon sakabula nwon fo sobu oyinbo kan lati ko eru re, sugbon awon irin ti nwon fi di gaga ko jeki nwon le je oja na run.

Lairotele awon ogun olopa de pelu ihamora ogun afonja kan ti awon olopa ju si arin won, enia merin ni nwon pa ni apafon, nigbana ni eru bawon, ti won tuka olukuluku si gba ibi ona tire salo

Oyinbo kan ti o nlo si Yawenda ti awon janduku nwonyi pade loju ona, nwon fi kondo ati kumo ba moto re je, oyinbo na je okan ninu awon onise ijoba ni ilu Buea, lowolowo ti a nwi yi, awon olopa ti bere si lepa awon oni onisunmomi na.

## Omobinrin Kan Sonu Fun Odun Metalelogoji

Okunrin kan ti nwon npe ni Sekoni ni gbogbo awon enia mba yo ayo ti omo re obinrin ti o pada wa sile lehin odun metalelogoji.

Ni odun 1917 ni a gbo pe pe omo na ti sonu nigbati o nlo silewe, ko si ibiti nwon ko wa omo na de, on nikan soso lowo iya ati baba re.

Lehin na ni igba yi fun baba omo binrin yi, ti awon L. E. D. B. si gba gbogbo ile baba re ni Oko Awo oba okun, ona osa, pabo ni. Nigbati o se ayipada rere de, o kole, o kanse sugbon ko bimo miran.

Ni owuro ojo kan ninu osu ti o koja ni obinrin kan wa mbere Sekoni, nigba ti awon mejeji ri ara won won ko mo ara won. Sekoni bere wipe kini oruko re ti o nje? O si dahun pe on Wosifatu ni, Heu! Alake? O si dahun pe emi na ni iya mi da? Sekoni ba pe iya re pe, wa o Siata, wa wo ohun ti mo ri yi, omo re de gbagi ti nwon di mo ara won nse ni omi mbo loju won.

## Enia Dudu Kan Wo Egbe Alasodun Ilu Oyinbo



Enia dudu kan ara ile Ghana ti enu re dun si oro siso, oruko re nje Ogbeni E. Koffi Davies, o je fun lo silu Oyinbo, nwon se siso kan ninu eyiti nwon pe Koffi pe ... o wa soro Oro enu re dun tobe ti nwon fi gba sinu egbe alasodun.

## Ati Tete Ku Nibiti O Nta Tete

A gbo irohin wipe ni ojo isinmi (Sunday) ti o koja ni Ola Oyingbo, Ebute Metta, ni awon janduku onitete meji joko lati ta tete ni osan gongon larin ojo yi. Nibiti won gbe ti nta tete yi ni oro gbe se bi oro larin awon mejeji ti won si fi ija peta.

Ki ama ba opo lo ile Olaro, lehin igbadie ti won ti bere ija na, okan ninu won subu, o si ku. Nigbati nwon ma fi de ibe won ba pelu ogbe ni igbaya re.

Gegebi irohin ti a gbo ni ogba awon olopa ni Ebute Metta akoko ti awon olopa nse iwadi nipa oro na ni wipe Ogbeni kan ti o nlo ise ise moto wiwa, Disu Ajadi ti o ngbe No. 43, ni Opopo Orisan l'Eko, ni awon olopa da duro fun ibere. Ogbeni ti o ku na nje Salawu Aremu, oku re si wa ni ile iwosan nla ti Eko. Awon Olopa si wa lenu iwadi oro na.

## EGBE NAWAIRU-DEEN SI EKA EGBE WON SILU ENUGU

Lojo Sunday, 17th osu April 1960 ni awon omo egbe Nawairu-Deen ti Abeokuta da eka egbe won sile ni ilu Enugu Mallam Umoru Adisa, ti ise Mayor ilu Enugu lo se Alaga idasile na.

Nigbati Mayor Enugu nsoro, o ba awon omo egbe na yo gidigidi fun idasile egbe won titun yi si apa ipinle Ila-Orun, ti o je agbegbe ibiti o ye ki ako awa Musulumi gbile lasiko yi.

(Wo yoku loju ewe keje)

LIVE WELL
EAT WELL
eat
"De FACTO"

## Agbere Agbeju Esin Fi Da Baba

Lati owo Mustafa Balogun

Nigbakan, ni akoko laelae, eiye Akoko nikansoso ... gbere-gbere, bi ... ba ku, eiye Akoko ni yio gbe Posi re, nipa ... o di ... nla, o di ... o si di olowo.

Lojo kan eiye Akoko ... o nseleri lati ... awon eiye, o wipe ... ti alagbede ba fi ... a ma daraju ti elomiran ... nitorina, lojo ti iya ... ba ku posi irin ni on yio fi sinku re.

Gbogbo awon eiye lo ... ara won, ko si eniti o le ja ... nitoripe gbe... ni. Eiye di nikan ... wipe, iro lo pa ko le sese.

... dahun pe "Agbere ... esin fi da baba. ... pe, agbere ni eniti o ... ori ewe. Bi ... ba te, a ni ki awon ... sinu osoro ejo.

Laifa ... ran, iya eiye Akoko ku, awon eiye wa ... akoko ti eiye Akoko yio ... posi irin de. Nigbati eiye Akoko de idi irin a fi ... so kin ngogo enu re ... siam.

Nigbati oku iya ... ni nlo bi ... ojo mefa ti ko si posi irin, oorun Oku iya Akoko ko jeki awon gbadun ni awon ba wa aloku posi kan ti nwon fi sin iya Akoko.

Ko da posi ti nwon fi sinku iya eiye Akoko, ko dara to ti iya Olokose. Eyi lo mu Ajapa ti o fi pa owe bayi pe,. Agbere ni ti iya alakara, nwon ni akara re ti oni ma dun ranyin ranyin bi oyin o fi iru ali ndan?

Iya alakara dahun pe beni, mo fi iru si, mo fi ogiri si. Bawo ni ogiri se de inu akara.

## Awon Onifayawo Tun Ngba Ona Miran

Lona papo ni a gbo wipe Ijoba ti yan awon Onibode s'oju ona lati ma dena lati mu awon Onifayawo. Nwon nde ona fun won lona Ijofin, Lona Agbamola, lona Idiroko, lona Shaki, lona Yasikira lona Fenandopo, lona Buea ati lona Birnin Kebbi.

Sibe-sibe, bi ijoba ti nse toyi, awon Onifayawo ko dekun ise buruku won yi Ijoba si ti nwa ona ti awon tun ngba, sugbon pabo ni.

Asiri na wa tu laipe yi, nigbati awon Onifayawo ko apoti issna mejidlogbon ati apoti siga mesan sinu oko moto kan ti o nko awon ero lati ile Kamerun lo si ilu Maidugari nibiti ijoba ko tile foju si pe iru nkan be le sele. Bi moto yi ti nlo ni jamba sele si, nigbati awon olopa de ibe awon meji ri owo ba nipa fayawo. Gbogbo eru ti awon gba lowo won je egbaji Poun.

Eo ri pe ko si ona ti awon Onifayawo ko le ba wo o.

# Gomina Titun Ti Ile Kenya



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Ogbeni Sir Patrick Muir Renison K.C.M.G. ti o ti fi akoko kan je oye Gomina ni ile British Guiana, sugbon nisisiyi nwon ti fi je oye Gomina si ilu Kenya.

Yio bere ise nilu Kenya ninu osu October, odun yi,

## DR. DIKE FE DI ALA BOJUTO UNIVERSITY COLLEGE IBADAN

—o—

Larapa irohin kan ti a ri gbo wipe Ogbeni Parry ti a ti gbo wipe on lo ti nse olori alabojuto Ile eko Ibadan University College ri fe gba isinmi kuro lenu ise na lo sile a si gbo wipe boya ni yio tun pada wa mo.

Nigbana, tani enia dudu ti o to mu iru ipo bayi dani? Awon Igbimo wa ro si eto wipe Dr Dike ni ipo na to si, gbogbo won si panupo le lori.

Lori eyi ni baba iyawo Dr. Dike se ase nla kan lati fi se ayesi fun oko omo re. Die ninu awon gbajumo to wa sibi ase na ni oba ilu Onitsha, Alufa eni owo C. J. Patterson, Monsignor John Obalagu.

Omo Oninkan papa Dr. Kenneth Dike ati iyawo re wa sibi ase na.

**Kere ! o**

A ti ni orisirisi egbogi fun arun Inarun ati arun Jedijedi, (Bitter Tonic Liquid of Life) Tete wa ra tire, t'okunrin ati t'obirin ki o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORE

7 Egerton Road, Lagos

HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Talisman, Charms, ... Faithful Reproductions of Hindu Gods in the ...

Enclose ... by Air Mail for Catalogues and Literature.

HINDU SANKARA, ... London, ... England

## Jamba Moto Sele

Onimoto kan ti o nwa moto lo lori ere loju opopo ona Katsina, bi o ti nlo lori ere na, pelu awon ero inu oko na lairo tele, ni irin ti nwon mu dani ti nwon fi nlo oko na kan ghau, ni moto ba ya bara o fi ori le inu igbe.

Dereba moto ti irin itoko na kan mo lowo, ati eniti o sike'l Dereba na ti nw n jeko niwaju ti nwon njija-du lati ja bo sile, awon mejeji ni moto na pa.

Sugbon awon ero inu moto bi iwon enia merinle. lorun fi ara gbogbe, nigba-ti moto na lo fi ori so igi ninu igbo. Gbogbo awon ero oko na ni nwon ko lo sile Alaisan ni igboro ilu Katsina.

## Egbe Nawairu-deen Si Eka Egbe Won Silu Enugu

Awon omo egbe yi, ti o wa lati Abeokuta si Enugu lati si eka egbe na ni, Alhaji Makanju-Ola Alufa H.Y. Dindi, Raji Alade, R.A. Bello Olayesi, B. Akinsanmi, B.A. Dawodu, G.A. Fabunmi, S.O. Lawal, ati S.A. Okanlawon awon ni o se eto idasile eka egbe ti nwon da sile ni Enugu, eyi ni yio so eka egbe na di ogorin ilu ti a ti da egbe Nawairu-deen sile lati odun 1939, eyiti o je Olori lati Abeokuta.

Nwon tun se alaye siwaju pe iye awon ilewe ati ilekewu ti nwon da sile ni ipinle Iwo-Orun ipinle awon Hausa ni ile Nigeria ati nile Ghana lati odun 1944 si odun 1959 je merinlelogorun. Ati nipa iranlowo arakunrin wa Hassan Akiyode, ni nwon fi si ilekewu kan nigboro ilu Kano ti nwon fi egbaa ponun ko laipe yi Lowolowo yi, egbe yi ti ko ile eko nla kan sile Abeokuta (Elementary Teacher Training Centre) nwon si tun nko ile eko giga kan lowo nlaisiyi si oju ona Ibadan ni baso mokandiladorin.

Nipari oro na, Mayor Enugu so pe, awon egbe ti Enugu yio ma ri iranlowo lati odo on ni gbakigba ti o ba ye, nwon si pinnu wiye kakiri ilu Enugu ati ni agbegbe re, nwon o da ilewe ati ile kewu sile.

## ENIA KO LE BI'MO LAI NI OYUN

(Obere lati oju ewe keji)

Nwon ki wipe o ku iwo omode o, o si dahun pe o o, e se o. Nwon bere pe ni ojo wo lo bimo yi? o dahun pe o to iwon osu kan abo. Tani baba omo omo na? O lo silu Oyinbo. O to akoko wo ti o ti wa nileyi? Howu o to odun marun. Nigbawo ni o lohun ti awa ko ri o ibe ni oro pesi je. Nwon ranse pe eniti omo re sonu. Bi o ti de lo ri omo re, o ki mole, ni awon Olopa ba ti Amoke mole. Nwon koiti se ejo re.

## E MASE FI OMI S'OFO




E wo eniti o nfi omi ero fo ese re nidi ero omi ati obinrin ti o yi ero ti omi ti kun inu koroba re ti ko bikita ti omi na nwo danu yi. Nwon fi omi sofo, eyi si le ma jeki a ri omi lo fun anfani arawa to bi a ti nfe.

Emase lo omi s'ofo

## OLOMOLANKE KOBIKITA DEREBE KO SE SURU

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT DRIVER




Okunrin Olomolanke ti a awoyi lo ... eru ala banta-banta, nigbati awon egbe re fe ran lowo lati ba ti i, o le won kuro wipe on yio se afowofa funra on. Sugbon eru apo gari na a wuwo, ko si tun mo ofin oju ona moto.

Nibiti o gbe mba moto du ona, olomolanke Kolu onikeke, o si se e lese.

# WNTV-WNBS

## Awon Elero Gbohun-gbohun ati ti Alaworan Naijiria fi idunnu se ikede pe nwon yio si

# Ile - Owo Ẹrọ Gbohungbohun Kini ni Naijiria

## NI OLA OJO OSE TI ISE ỌJỌ KINI OSU KARUN ODUN YI

## YI ERO GBOHUNGBOHUN RE SI:

602 Kilocycles
498 Metres ) Ni agbegbe Eko

656 Kilocycles
457 Metres ) Ni agbegbe Ibadan

Printed and published by the Union Printing & Publishing Company 25, Kosoko Street, P. O. Box 467 Lagos Phone 23330